“Ẹni kan kan ninu yin ko nii gbagbọ ni ododo titi ti yoo fi nífẹ̀ẹ́ mi ju baba rẹ, ati ọmọ rẹ, ati awọn èèyàn ni apapọ lọ”

Lati ọdọ Anas- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ẹni kan kan ninu yin ko nii gbagbọ ni ododo titi ti yoo fi nífẹ̀ẹ́ mi ju baba rẹ, ati ọmọ rẹ, ati awọn èèyàn ni apapọ lọ”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ fun wa pe Musulumi ko nii jẹ ẹni tí igbagbọ rẹ pe titi ti yoo fi ti ìfẹ́ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣáájú ìfẹ́ ìyá rẹ, ati baba rẹ, ati ọmọkùnrin rẹ, ati ọmọbìnrin rẹ, ati awọn èèyàn ni apapọ, ìfẹ́ yii n beere fun itẹle e ati riran an lọ́wọ́, ati ki èèyàn ma yapa rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5953